



# Irohin Yoruba

Vol. XII No. 587 SEPT. 3 — SEPT. 9, 1956 KOBO MEJI (24)

**FUN T TA**

[illegible]

**J O Shoyinka.**

[illegible]

# IGBIMO OLUWADI BANKI AZIKIWE TI BERE IPADE



Ololа Stafford Foster-Sutton Oga Adajo Agba Apapo Ijoba Naijiria, Alaga Igbimo Iwadi Oran African Continental Bank bi o ti nsokale ninu moto re lati wo Ile Igbimo-Nla Asofin Ijoba Naijiria nibiti nwon yio ti bere ipade iwadi na.

**EKO—Ni ojo Aje ti ise ojo ketadinlogbon osu kejo odun yi ni awon Igbimo Oluwadi African Continental Bank ti bere ipade won akoko ninu yara ibiti awon Igbimo Apapo Ijoba gbe njoko se ipade ninu Ile Igbimo Nla Asofin Ijoba Naijiria l'Eko.**

Nigbati ese won pe tan ni deede agogo mokanla aro ni nwon bere, bi eto na yio ti se lo si, Olola Stafford Foster-Sutton, Oga Adajo Agba Apapo Ijoba Naijiria ti o se Alaga Igbimo Iwadi na si se alaye fun gbogbo awon agbejoro lotun losi pe Alagba Olola Alan Lennox-Boyd ti ise Asoju Ijoba Geesi fun gbogbo awon ilu abe Ijoba Geesi ni o gbe ise iwadi yi fun on lati se Olori Igbimo Iwadi lori esun aisedeede Dokita Nnamdi Azikiwe Alakoso Ijoba Ipinle Ila-Orun pelu African Continental Bank.

O si la a ye won pe ise pataki na ti awon ni lati se iwadi re lesese gegebi ase ti Alagba Olola Lennox-Boyd gbe le on lowo na ni yi:—

(a) Esun aisedeede ti nwon fi kan Dokita Nnamdi Azikiwe, Alakoso Ijoba Ipinle Ila-Orun lori ifarakora on pelu oran African Continental Bank Limited.

(b) Awon nkan to fa a, ati bi nwon ti se gbero re ti igbekele okowo Eastern Regional Marketing Board ti se koja si sakaani Eastern Region Finance Corporation ti o si mu ki oran na fi de aye kiko owo okowo ibe lo si African Continental Bank Limited.

(d) Idarapo Dokita Nnamdi Azikiwe l'ona taara tabi l'ehin-o-rehin pelu African Continental Bank Limited, awon olutu Banki na, awon alabapin re, tabi awon osise ibe nigbagbogbo, yalаa ki nwon to fi owo yi

*Wo oju ewe kejila*

## Gbomogbomo kan tun j'omo gbe

YABA-EKO.

NI osan ojo Aje ti ise ojo ketadinlogbon osu Kejo odun yi ni okunrin ara Ilorin kukuru kan, ti o gun ni ese marun, o to ẹni odun marundinlogota ti o pe oruko ara re ni Kojere Hausa tun ji omo odun merin kan ti baba re nsise labe Relwe ti nwon npe ni Rafiu Alani Ishola, gbe ni ojude 93, Old Yaba Road nibiti iya omo na gbe fi omo ... ... oja re.

Bi iya omode na ti de ti ko ri omo re Rafiu ni ati igbale mo, ni o ba fi labe ta pe, "Aladugbo e gba mi kale nko ri Rafiu! abi tani mo ibi ti o gbe xba o?" Bi iya omo na ti nkigbe yi lowo ni o fajokan wo okere ni o ba ri awon kan ti nwon pejo le e lori pelu omode ni odo re ti awon enia mbere lowo okunrin na pe "kini o ti fe pelu omo ti o fa dani?"

Ejo ti o ri ro ni pe on nfe lati fi emu p'orumagbe ni on ko si mo ibiti awon elemu nso si, ni on ba be omo na lati fi ibiti nwon gbe nso si han on, bi oran ohun ti s pa on pelu omo na po ti je niyi o.

Lesekese ni nwon ti ... ifura si ajomogbe ara Ilorin na, nwon si ranse pe awon olopa. Bi egan, nwon de ... ... ...

*Wo oju ewe kejila*

## AKINTOLA F'OTITO ORO TE AWON OLOTU IJOBA LARA

OLOYE S. L. Akintola ti ise Gbakeji Olori Apapo Egbe Afenifere ati Ogagun awon Egbe Alatako ninu Igbimo-Nla Apapo Ijoba Naijiria, gba awon Olotu Ijoba ni gbolohun lori owo ti Ijoba fe ma a na lori igbadun awon Asoju Igbimo Ijoba na pe "Awon ti o ran awon wa sinu Apapo Igbimo yi ko ran awon wa lati ma a lu owo ilu ni pompo, lati ma a wa na a ni ina apa, ina tani o le bi wa lere, nitorina ki enyin Olotu Ijoba sora gidigidi lori eto inawo ti ko le dun mo ara ilu ninu lati gbo, ki a si ma a ranti nigbagbogbo pe, awon ti a nse asoju fun ninu Igbimo-Nla yi ki ise awon omugo o."

Ninu ipade Ajo Igbimo-Nla Apapo Ijoba Naijiria ti nwon se koja yi ni Dokita K. O. Mbadiwe, Minista Alamojuto ise Isoro-sokere ati ti oko ofurufu ni ojo Eti ti ise ojo kewa osu kejo odun yi gbe eto kan ti awon Olotu Ijoba na ti se kale fun apero awon asoju Igbimo-Nla na.

Eto ti Ogbeni Mbadiwe gbe kale na ni pe ki Ijoba bere si fun awon Asoju Igbimo kookan ni egberin ponun lati ma a fi ra moto ayokele. Bi Ijoba ba yonda fun gbogbo awon asoju mejidiladosan (168 members) lati gba owo yi, gbogbo owo ti nwon yio gba ni lati je egbaa metadinladorin o le irenwo ponun (£134,400) laika ti awon Minista mewa ati awon Akowe Igbimo (Parliamentary Secretaries) mefa ati awon Asoju pataki meta, awon wonyi ti koko yanju tiwon siwaju ati pe inawo yi ko duro mo nibe nikan, Ijoba a tun ma a san ogoje ponun (£140) owo irina (travelling allowances) na fun asoju kookan lodoodun.

Bi nwon ti gbe imoran yi kale fun apero ni Oloye S. L. Akintola, Asiwaju Egbe

*Wo oju ewe keta*

## Gomina-Agba gba Awolowo l'alejo

EKO.

NI ojo 'Ru ti ise ojo kokandinlogbon osu kejo odun yi ni Oloye Obafemi Awolowo Olori Egbe Afenifere ati Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun wa ki Gomina-Agba Apapo Ijoba Naijiria, Olola James Robertson pe o ku-abo dide ti o de lati ilu Oyinbo fun aye isinmi ti o ti gba lo sile.

Gomina-Agba na si fi onje-osan se Oloye Obafemi Awolowo na l'alejo, nwon si jijo jiroro die lori eto iselu ki Oloye na to fi ibe sile. Oloye na se to wakati meta ti Afin Gomina-Agba na ni Eko ki o to kuro nibe.





SEPTEMBER 3RD TO 15TH

UNION TRADING CO. LTD.



# EYI NI OJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

### OJỌ IṢẸGUN 4TH SEPTEMBER (TUESDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo Ejinrin. |
| Abẹokuta. | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasinmi. |
| Ibadan | Ogunjana, Lagun, Sagbẹ, Olode |
| Ijẹbu | Aiyepe Sagamu Itaosu Ogere Irolu Itele Ita-Iloti |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha Ibodi Ibode Kajola Oluwa'da, Eti-Oni |
| Ondo ati Eti Odo | Oka Ilara, Abigi, Aiyetoro, Ẹpẹ. |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro Jigga |
| Ogbomọsho | Obada Gambari |
| Ekiti | Ilogbo. Oke-Aiyedun Idogun. |
| Ibinni | Eko |
| Delta | |
| Igbajọ | |

### ỌJỌ 'BỌ 5TH SEPTEMBER (WEDNESDAY)

| Ilu | Oruko Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Ọbun Eko |
| Abẹokuta, | Atan Agbado Ito Itoku Isabo Ọdẹda, Ibara, Itori |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressi Obada Egbeda Oyedeji |
| Ijẹbu | Ilishan, Odogbolu Atan Imope Ishan Isara Imodi Ajegunlẹ |
| Ijẹsha | Esa-Oke Ilase Epe Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo Igbotako, Ileoluji Obunkekere Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro. Tata Randu Ado-Odo |
| Ogbomọsho | Irẹssa-Du Arolu Egbẹda |
| Ekiti | Egosi. Odo-Aiyedun. |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajọ | |

### ỌJỌ 'RU 6TH SEPTEMBER (THURSDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin, Ebute Ikorodu |
| Abẹokuta. | Owode Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ. Omida, Ilawo Owowo Obafẹmi |
| Ibadan | Ọja-Oje |
| Ijẹbu | Ikẹnnẹ Okun-Ọwa, Eruwọn. Omu, Mamu |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha. Oshu. Itagu. Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode, Odoko. |
| Ondo ati Eti Odo | Agbabu. Igbogi. Ishua. Erinkẹta |
| Egbado | Olorunda. Kajọla. Ilobi. Eredo |
| Ogbomọsho | Arasomi, Irẹgba Ẹrẹkẹsan. |
| Ekiti | |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajọ | Iloro. |

### ỌJỌ ẸTI 7TH SEPTEMBER (FRIDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege Ikẹja. Ebute-Ero, Ọjọ, Ajido |
| Abẹokuta. | Lafẹnwa Obada Ọba. Kajọla. Ajegunlẹ, Idogo, Ogumaki |
| Ibadan | Ibuko Lalupon |
| Ijẹbu | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye. Ijesha-Ijẹbu. Isara. Imodi. |
| Ijẹsha | Esa-Oke, Iware, Ejioro, Odo. Ibokun, Esa-Odo, Ijẹda, Ikeji. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunrẹn, Atijẹrẹ. Oni, Ebiwo. |
| Egbado | Idi-Emi. Ibeshe. Lasilọ. Atta |
| Ogbomọsho | Oko. |
| Ekiti | Ifaki Okemesi. |
| Ibinni | Uromi. |
| Delta | |
| Igbajọ | |

### ỌJỌ ABAMẸTA 8TH SEPTEMBER (SATURDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo |
| Abẹokuta. | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasimi. |
| Ibadan | Olode. Ogunjana Lagun |
| Ijẹbu | Aiyepe Sagamu Ita-osu Ogere Irolu. Ita-Iloti, Itele, Oyingbo. |
| Ijẹsha | Ijebu-Ijesha Ibodi Ibode Kajola, Oluwa'da |
| Ondo ati Eti Odo | Abigi Aiyetoro Oka Ilara Epe |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro |
| Ogbomọsho | Obada. Gambari |
| Ekiti | Ilogbo. Oke-Aiyedun Idogun. |
| Ibinni | Eke. |
| Delta | |
| Igbajọ | |

### ỌJỌ AIKU 9TH SEPTEMBER (SUNDAY)

| Ilu | Orukọ Awọn Ọja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun-Eko |
| Abẹokuta. | Atan, Agbado, Ito, Itori. Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara. |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iressa Obada Egbẹda, Oyedeji |
| Ijẹbu | Ilishan, Odogbolu, Atan. Imope Ishan, Iṣara, Imodi, Akẹsan |
| Ijẹsha | Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko, Erinmo, Esa-Oke |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun, Odojomo. Igbotako, Ileoluji, Ọbunkekere. |
| Ẹgbado | Aiyetoro Tata Randu Ado-Odo |
| Ogbomọsho | Iressa-Du. Arolu. Egbeda Jabata, Oke Imale |
| Ekiti | Egosi. Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajọ | |






# A. B. D. Olowe

*(Lati owo James Ade. Afọlabi-Ibiran)*

A—Abamọ ka maṣe r. a ṣe e tan o di apọn.

B—Bi oju ri enia a dake.

D—Didun lodun la ṣiṣe ọrẹ f'ẹfọ f'ilu Oje lo Oge je.

E—Eru l'ogbe, irungbọn l'agba, mamu ni ti afojudi.

E—Eni ti agbara pa lo po, eni ti ọgbọn pa ko to nkan.

F—Funfun l'ẹyẹ ngu, ki i gu dudu.

G—Gele o dun bi ka mo we, k'a mọ we ko dun bi ko ye ni, ko ye ni ko dun bi ka ri owo ra a.

GB—Gba were nko gba were l'oja fi nho.

H—Hanha ni ọgọlọ fi ga ju alamu lọ.

I—Ibi ko yato si ibi bi nwon ti bi ẹru ni nwon bi ọmọ.

J—Jakumo ki i rin ni ọsan, eni a bi re ki i rin loru.

K—Kini apari wa de iso onigbajamọ.

L—L'ọjọ are ni oro ndun ọlẹ.

M—Moriwo ko woju enikan a fi Olọrun.

N—Ngo ṣe iya ko le jọ'ya, ngo ṣe baba ko le jọ baba, wo iso de mi ko le jọ oniso, oju mẹwa ko jọ oju ẹni.

O—Odidere ẹiyẹ okun, aluko ẹiyẹ ọsa.

Ọ—Ọmọ ti ko ni oniberu ni i bajẹ.

P—Pipe ni a npe gbọn a ki i pe go.

R—Riro ni t'enia, ṣiṣe ni ti Olọrun.

S—Ṣaṣa enia ni nfẹni l'ẹhin eni, ti aja ti ẹran ni i fẹni l'oju ẹni.

T—T'oju t'iyẹ ni aparo fi i riran.

W—Werepe ko ni ibikan agbamu, gbogbo ara ni i fi jo ni.

Y—Yinniyinni ni i ni k'eni ṣe'mi.

## Idanwo Idaraya f'awọn ọmọde

*(Lati owọ J. Adegoke, Ile Alara, Ishoko-Egbo.)*

FI ỌGBỌN ORI DAHUN EYI

BABA kan ati iya kan joko nidi tabili ijẹun, baba joko koju si iya. Ilakanna ni awọn ọmọ wọn ti nje Alaba ati Dada joko lodo wọn. Alaba joko legbẹ otun baba ati Dada legbe osi baba.

* * * *

IBERE

1. Awọn melo lo wa n'idi tabili?
2. Egbẹ wo ni Alaba ko si Iya?
3. Tani o wa legbẹ ọtun Iya?
4. Kini nwọn fẹ ṣe ni idi tabili na?
5. Tani Alaba koju si?

Kọkọ dahun ibere na funra-ara rẹ na ki o to wa wo idahun na ni isori kodo ni isalẹ.

* * * *

IDAHUN

1. Mẹrin (4)
2. Ẹgbẹ ọtun
3. Dada
4. Nwọn fẹ jẹun
5. Dada

## Ọrọ iyanju

*Lati oju ewe kẹwa*

awọn enia pe ki ẹ ka Iwe Korinti Kini ori 9 ẹsẹ 27 emeta pẹlu ironu arojinlẹ.

### Ọrọ na niyi

"Ṣugbọn emi npon ara mi loju, mo si nmu u wa sabẹ ilẹriba: pe lẹhin ti mo ti wasu fun awọn ẹlomiran, nitori ohunkohun, ki emi tikara mi maṣe di ẹni itanu."

Eni ba ni eti lati fi gbo ki o gbọ. Iṣẹ nyin ki yio jasi asan niwaju Oluwa, Olotu. mo dupẹ. o si digba kan na o.

# Igbimọ Oluwadi Banki bẹrẹ ipade

*Lati oju ewe kini-*

sibẹ tabi lẹhin ti nwọn ti fi sibẹ lan ni nkan ṣe pẹlu ọran na ti a ti sọ siwaju:

(e) Idapọ ti o wa larin Eastern Region Finance Corporation ati African Continental Bank Limited lori gbogbo ọran ti a ti so siwaju yi.

(ẹ) Idapọ ti o wa larin ẹnikan tabi akojọ enia tabi ẹgbẹ ti o fi idi mulẹ tabi eyiti ko fi idi mulẹ ninu eyiti Dokita Nnamdi Azikiwe ni tabi ti o ti ni itara ajumọṣepọ pẹlu rẹ tẹlẹ ri, yalaa l'ọna taara tabi lẹhin -o-rẹhin ati African Continental Bank Limited.

(f) Ọna ti nwọn ngba lo gbogbo orisun-owo ti o ti nwọ African Continental Bank Limited, yalaa ki nwọnto fi owo ti a sọrọ ba ni ese (b) yi sibẹ tabi lẹhin igbati nwọn fi sibẹ ti le je pataki si ninu iwadi ti a fẹ ṣe yi.

Yalaa ninu ọrọ ti a so soke yi, boya a le ri ẹniti yio s'aiya gbangba ninu awọn to di ipo Minista mu tabi iṣe Ijọba, ṣe ohun ti o lodi si ofin aye ipo bawọnyi, ti o ba ri bẹ ẹ ni ona wo ni.

Nigbati Alaga na pari alaye yi tan ni gbogbo awọn amofin ti nwọn wa si ibe wa bẹrẹ si f'arahan fun Alaga Igbimọ Iwadi na, ẹniti awọn wa ṣe agbejoro fun. Dokita Nnamdi Azikiwe ni awọn loya tirẹ lọ-jara. Ogbeni E. O. Eyọ na ni tirẹ bẹ ẹ. Gomina Ipinlẹ Ila-Orun ni tire lọtọ beni awọn Igbimọ Oluwadi paapa ni ti wọn pelu. Diẹ ninu wọn fesi si alaye Alaga na.

Esi ti Ọlọla Frank ti iṣe asiwaju awọn agbẹjoro Dokita Azikiwe, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun fi si alaye Alaga Igbimọ Iwadi oran African Continental Bank na ni pe ki nwọn tete bẹrẹ si iwadi na ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ogbonjọ oṣu ti o kọja yi.

Ṣugbọn Ogbeni Mackenna, asiwaju awọn agbẹjoro fun awọn Igbimọ Oluwadi oran na ko fi ara mọ imọran na. O ni ko ni i ṣe e ṣe lati gbọ eto ọrọ gbogbo awọn ẹlẹri tan ki o to to ọjọ oni— Ọjọ Aje, ọjọ kẹta oṣu yi. O ni ki awọn ẹlẹri na maṣe jafara lati ko ẹri wọn sile ki nwọn si tete fi le akowe awọn Igbimọ Oluwadi ọrọ na lowo ki nwọn ba ni asiko to lati ka a yeke-yeke.

Ogbeni Shawcross asiwaju awọn agbejoro Ogbeni Eyọ so fun awọn Oluwadi na pe ki nwọn se e ni ileri fun on pe nwọn yio jeki akowe iširo-owo (accountant) kan ti yio de lati Londonu fun iranwọ Ogbeni Eyọ ninu ọrọ na ye awọn iwe iširo-owo ti nwọn fi nsiṣẹ ni ile-itaju-owo (Banki) na wo finifini. O ni bi akowe iširo-owo na bati nse eto tọtọ lori awọn iwe na ni ki awọn agbẹjoro nạọa ma ṣe afinto lori awọn iwe kanna. Ọlọla Stafford si ne on ko ro pe idaduro tabi ifasehin le wa ninu eto yi.

Gbogbo ijoko ti o wa ninu Ile Igbimọ Nla na ni o kun fun awọn enia ti nwọn wa wo bi nkan wọnyi ti nlọ si. Bakanna ni ero kun ita gbangba Ile Igbimọ Nla na lati le ri awọn enia patakipataki ti nwọn wa si ibẹ. Alaga Igbimọ Iwadi na si fi ibẹrẹ gbogbo ọrọ awọn ẹlẹri na si ọjọ oni (3-9-56). Bi nwọn ba ti mba a bọ si e o ma a gbọ o.


## ẸNYIN AGBẸ ONIKOKO Ẹ RANTI



*Ja gbogbo apopo koko ti o ba bajẹ kuro ki ẹ si ma a ri wọn mọlẹ ki ẹ si ma a fun*

**'PERENOX'** TABI **'PEREPOD'**

*s'ara igi koko l'ọsẹ kẹta-kẹta*

**Ki arun korikori ma ba a gbe Koko ati Owo nyin lọ**

Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun mẹrinla (14 lb) ni "PERENOX" wa
tabi
Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun meji (2 lb) ni "PEREPOD" wa
Pẹlu oṣuwọn ati iwe apejuwe kekere l'ọfẹ
Didi ni awọn Garawa ogun na wa lati ri i daju pe nwọn wa ni ẹkun rẹrẹ ati pe ko ma fi le bajẹ rara.
Kii pa enia ati awọn Ẹranko l'ara bi awọn ba loo l'ọna t'nwọn ṣe apejuwe lilo rẹ

O wa kakiri ẹka ile iṣẹ ati lọdọ awọn aṣoju
THE COOPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION
tabi
THE UNITED AFRICA CO. LTD

Plant Protection Ltd.



**KO SE MA NI!**




Iṣe agbayanu awọn Woli lalai to kun fun ohun ajo. Adura Ilontu ati orisirisi ohun Ala Owo rẹ je 15s. A si tun nta kọkọro 6th and 7th Books of Moses. Abela Adura, Turari Ajebina. Iwe Adura orisirisi. Here fun iwe itaja. Ifilo pataki: A gba awọn onibara wa ni iyanju, ki won sora lowo awọn ẹniti nma nlo oruko wa lati fi polowo oja won.

Awọn ile ise wa niyi:—
36, King George Avenue Yaba ati 15, Araoti Street, Yaba ati 83 Idikan Street, Ibadan a ko si ni ile ise miran jube lo.

THE MANAGER,
36, King George Avenue,
YABA.


Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Ltd 5/7 Apongbon Street, Lagos Editor: S. M. Ademuyiwa 9 Chapel Street, Lagos

## Ọlayiwọle bimọ

EKO.

NI ale ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu kejo ọdun yi ni Ọlọrun fi ọmọde-kunrin kan ta Ọgbẹni Esekiel Ọrẹ Olayiwọle ati iyawo rẹ Hebecca Ebun Olayiwọle lore.

Lati ale ọjọ ti nwọn ti bimọ na titi di ọjọ ikomọ ni awọn ti ngunawo, beni Ọlaiya ọrẹ baba ọmọ paapa ko si rẹhin ninu inawo abọlamọyọ na. Ọlọrun a pin'ri kari o.

# Ẹgbẹ Imọlẹ yayọ Ajọdun Kẹrinla Igori-Oke

*Agẹlu-Jerusalem- Ado-Awaye*

NI ọjọ kẹdogbọn di ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu keje ọdun yi ni awọn Ijọ Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu, Agẹlu-Jerusalẹmu Ilu Ogo, Ado-Awaye Oke Ogun fi gun ori oke Oluwa lọ ṣe ajọdun kẹrin ti nwọn ti ngun ori oke na fun ajọdun adura. Ajọdun ti ọdunni dun ju gbogbo eyiti nwọn ti nṣe latẹhinwa lọ, nitori ayọ ti pọju larin awọn ti o tọrọ ti Ọlọrun si yọnda fun. Gbogbo enia ni o f'enu sọ jade pe Oluwa funra ara Rẹ ni o tẹ ilu na do.

Alaga Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu Oke Ogun ni o ṣe iwasu, ọrọ iyanju rẹ na wọ enia leti, bi ko ma dakẹ mọ ni. Baba Aladura, "Agbo Jesu" ti iṣe olori gbogbo wọn ni o ṣe adura. O si bẹrẹ si tọrọ ibukun Ọlọrun sori enia gbogbo lati ori awọn ọba, ijoye, Alakoso Ijọba, gbogbo Ijọ Ọlọrun ati gbogbo enia ni gbogbo aiye.

Ẹṣẹ awọn woli, awọn oluṣọ-agutan-Ijọ ati awọn asiwaju ẹgbẹ aladura gbogbo ni o peṣẹ sibẹ ti nwọn si ngbadun iio ati orin ti awọn Ẹgbẹ Imọlẹ ati Itọlẹhin Jesu. Bẹni Balogun Ẹgbẹ na Evangelist S. A. Abegunde nṣe bi "erin-ṣe losun" ti gbogbo rẹ ndun yungba. Awọn olori ati awọn enia pataki-pataki ti o ṣe alabapin ninu Isin Ajọdun ati aṣeyẹ na ti pọju ki a ma a darukọ wọn lọkọkan lọ. Aṣeyi-ṣamọdun-o.






## Adegbodu di Oliwo Ipẹru

IPERU IJẸBU-RẸMỌ.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni Ọba Alaiyeluwa Abraham Ọlayinka Okupẹ ati awọn oṣugbo rẹ fi Ọgbẹni Adebayọ Adegbolu jẹ Oliwo Ipẹru, Ijẹbu-Rẹmọ ni ile-awo Oṣugbo.

Awọn ti o wa si ibi ifijoye pataki yi ni Ọba Akufọn Idarika, Ọba Ẹbi Idena, Oloye M. A. Okupẹ, Agbonmagbe, Ọtunba Ipẹru, Oloye M. S. Sanusi, Balogun Ipẹru, Oloye J. A. Oremule, Jagun ati akọwe Kotu-Nla Eko, Aṣiwaju, Seriki, J. Olu. Gisanrin Ọbalokero, awọn Pampa ati awọn Olọpẹrẹ.

Ilu gbẹdu ni nwọn fi ṣe ikede ifiijoye na, awọn aṣoju Ẹgbẹ Afẹnifẹre wa sibẹ, bẹni ẹka Ẹgbẹ ọmọ-Oduduwa Ijẹbu-Rẹmọ ati awọn aṣoju Ẹgbẹ Ipẹru mẹrinlelogoji. Irohin ko to amojuba ni aṣeye oye na. Oye a mo'ri o.

## Oloye Ekwejunor-Etchie jare Lọya Ẹgbe

WARRI.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Ọgbẹni C. D. Onyeama Adajọ Kotu-Nla Warri da Ọgbẹni Webber Ẹgbe ọmọ Ẹgbẹ Alakuko (N.C.N.C.) lẹbi lori ẹjọ ti o pe Oloye Gabriel Ekwejunor-Etchie pe ki Kotu yọ o kuro ninu Ajọ Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nitori ọna ti nwọn fi dibo fun un wọle ko tọna taara.

Nigbati adajọ na yẹ esun ti Ẹgbe fi Oloye Ekwejunor-Etchie sun ati eyiti o sọ pe Olu Warri ni ọwọ ninu aiyederu na, o ri pe esun na ki iṣe bẹ rara ni o ba fi tu ẹjọ na ka ti o si ṣe idajọ pe ki Ẹgbe ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ na lọ san pọnun mejilelogogi owo irin-ẹsẹ fun ẹlẹjọ rẹ, Oloye Gabriel Ekwejunor-Etchie.

## YESUFU SE IJADE OKU BABA RE

IRẸSI Lẹba OSHOGBO.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu karun ọdun yi ni Ọgbẹni Yesufu Olagunju Balogun ṣe Ijade oku baba rẹ ti o fi'lẹ ṣe aṣọ bora ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu keta ọdun yi.

Inawo ọjọ na buaiya o le gongo, awọn alabaṣeyẹ wa lati orisirisi ilu, eniti o si ṣe alaga aṣeyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni S. A. Olawuyi, onjẹ lọ jara nwọn si fi ọti ṣe amuti, ero pọ bi omi bẹ ẹ ni ilu orisirisi lọ bẹrẹbẹ.

Diẹ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni S. A. Olawọle, Ọlọla S. A. Tinubu, J. B. Bamikọle, Yesufu Balogun, Lamidi Karimu, awọn omidan Aminatu, Sadatu, Safuratu ati awọn enia saraki-saraki.

*K'Ọlọrun fi ọmọ rere gbẹhin awa na o.*





Ẹ MA A POLOWO ỌJA NYIN SINU IWE Irohin Yoruba

E MA A KA IWE IROHIN
YORUBA NYIN NIGBAGBOGBO

# IBẸRẸ IPADE IWADI ỌRAN AFRICAN CONTINENTAL BANK NI EKO

















AWON OGBOLOGBO
(SCRAP)
OJE (LEAD)
IDE (BRASS)
BABA (COPPER)
AWON ALOKU IRIN
ERO MOTO (RADIATORS)
FAANU ATO (ALLUMINIUM)
JE OWO
Ko wọn wa ta fun
BUCK (NIGERIA) LTD..

THERMOGENE
EGBOGI IPARA








## Nathaniel Olude komojade

## ERỌ IṢERE AMẸRIKA TO DARAJU
Sinima inu ile (Home Cine Projector)



Ilera mi daradara



Andrews

L'oro




Fun tile inu nu

3/- 2/- 1/3

## Afọlabi ṣe ikomọjade

NI ọgbọnjọ oṣu karun ọdun yi ni Ọgbẹni S. A. Afọlabi ṣe ikomọjade ala-rinrin ọmọkunrin ti Ọlọrun n ta on pẹlu iyawo rẹ, Alice Adebowale lọrẹ. Tọna ẹsin igbagbọ, nwọn si so ọmọ na ni Kayode Arẹmu Afọlabi. Baba ọmọ na fi jijẹ te gbo-gbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati da-rukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Isaac Adeniyi, Azim Joseph, Ayandiran Azim, Jamiyu Areọye, Moses Adebamiji, Esrel Ogunniyi, Elijah Ọkẹ. Ire a kari o.




# ẸYẸ ISINKU GARU-BA PABMBARI

### Lati ọwọ Akanbi, Oke Masifa, Ogbomọshọ

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandilogbọn oṣu keje ọdun yi ni alagba Garuba Laoye ni Ile Ilode, ọna Ilorin ku, nigbati o di ẹni ọdun mẹrinleladorin (74 years) laiye. Iku rẹ na si dun ọpọlọpọ enia nitoripe ko ṣe arẹ ti o fi ku ati nipa iwa ikonimọra rẹ li o mu ki ẹdun iku rẹ o fi ka tọmọ-de-tagba lara.


ỌMỌ-ỌBA L. L. LAOYE
Ọmọ-ọloku

Ni ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn ọmọloku na, Ọmọ-ọba L. L. Laoye ati ẹgbọn rẹ ọmọ'ba J. L. Laoye wa lati Jos wa bẹrẹ isinku ni Ogbomoṣọ, inawo oku na pabambari nitori gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ibi oku na ni nwọn nsọ wipe irohin ko to afojuba ni inawo awọn ọmọloku na.

Gbogbo awọn ẹmọlẹbi idile Laoye ni o pe sibẹ, awọn ẹgbẹ ọdẹ Masifa, Busari Alamu ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ, Ọgbẹni J. A. Arẹgbẹ ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati Ilorin, J. A. Adeyanju ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati Ibadan, Lanipẹkun Akọwe Kotu ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ, Salawu Abidogun ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati Eko, wa pẹlu wọn ninu aṣẹyẹ yi.

Ọmọ'ba L. L. Laoye tun pe awọn ẹgbẹ Hasiri Masifa, nwọn si ba a kẹyẹ isinku na de ọja, ẹyẹ ọjọ na tun pabambari. Ọgbẹni Oyesola Alabẹde pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ wa lati Jos, Ọgbẹni Raji ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati Kumasi G.C. Awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ ni o rọgba yi ọmọ'ba L. L. Laoye ka titi nwọn fi fi pada dele.

Nigbati o tun di ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Ọmọ-ọba Laoye tun pe awọn ẹgbẹ Mejoriti ti Masifa nwọn si tun ba a jo lọ


GARUBA LADIRAN LAOYE
Ọrun're

* * * *

s'ọja, bẹ ẹ lo tun yẹ wọn talọ-tabọ bi igbati nwọn nṣe ajọyọ ọdun ni isinku na ri ko si ija ko si ita titi nwọn fi pari aṣẹyẹ isinku na. Ki Ọlọrun fi ọmọ rere gbẹhin gbogbo awọn alabaṣẹyẹ isinku na. Amin.

## NINA NI OWO

*Lati oju ewe karun*

wọn nigbati o wa laaye, nigbati otutu tabi ebi ba pa a ku tan, nwọn a f'ile ponti nwọn a fi ọna roka, nwọn a ṣe putuperẹ nibi oku obi ti iṣe ti ṣe l'oṣẹ ki aiye ba ri wọn lati yin won.

Kini iyi ati iyin ẹda nigbati ebi ti pa obi ku? Iru obi bẹẹ ko le sure fun ọmọ rẹ laiye ki o to ku, ambọsibọsi l'ọna ọrun' Iru awọn ẹni bẹẹ a si ma a ṣe fuari pe nwọn ṣṣnawo—nina l'owo. Awọn wọnyi ko fi owo na toju ara wọn, bẹni nwọn ko fi toju ẹlomiran; iwa ati iṣe wọn ko jẹki owo ti nwọn ni wulo fun ẹnikẹni, bẹni aiwulo rẹ yi ko mu ọla ati ogo wa fun Ọlọrun ti o fun wọn ni ẹbun yi.

*(Koi ti pari)*






